# JOHANNU BAPTISTI, AṢAAJU KRISTI

**Luku 1:1-25, 57-80; Matteu 3:1-12; 11:2-14; 14:1-12**

**ẸKỌ 16 --- FUN AWỌN ỌDỌ**

**AKỌSORI: "Gbogbo igi ti ko ba so eso rere, a o ke e lùlẹ, a o si wọ́ ọ jù sinu iná" (Matteu 3:10).**

### Ipa ti Johannu ninu Eto Ọlọrun

Johannu Baptisti kó àye ti o ṣe pataki kan ninu eto Ọlọrun fun irapada. Ọlọrun mí si awọn wolii majẹmu Laelae lati kọwe pe Oun yoo ran onṣẹ kan lati tún ọ̀na ṣe fun Messia Ẹni ti n bọ wa lati ra araye pada.

Gbogbo awọn wolii Majẹmu Laelae lo ti kú ni akoko ti a bi Johannu Baptisti. Fun irinwo ọdun, lati igba Malaki, ẹni ti o kọ iwe ti o kẹyin ninu Majẹmu Laelae, a ko fun ni ni ileri titun kankan mọ. Ṣugbọn awọn eniyan Ọlọrun ti wọn jẹ oloootọ wà ti wọn n duro de imuṣẹ awọn ileri Ọlọrun.

Awọn obi Johannu jẹ ẹni mimọ, baba rẹ si jẹ alufaa ninu Tẹmpili. Ni ọjọ kan nigba ti o n sun turari fun Ọlọrun, angẹli kan duro lẹba odọ rẹ o si wi fun un pe yoo ni ọmọ kan "yio si kún fun Ẹmi Mimọ́ … Ẹmi ati agbara Elijah ni on o si fi ṣaju rẹ̀ lọ" -- gẹgẹ bi Malaki ti sọ nipa rẹ fun ọpọlọpọ ọdun sẹyin (Malaki 4:5, 6). Angẹli naa wi fun Sakariah (baba Johannu) pe ọmọ-ọwọ́ naa yoo jẹ mimọ lati igba ibi rẹ̀, yoo si mú ayọ̀ pupọ ba eniyan pupọ. Inu Sakariah ati Elisabẹti dun pupọ pe awọn yoo ni iru ọmọ iyanu bẹẹ. Angẹli naa tun sọ pe orukọ ọmọ-ọwọ́ naa yoo jẹ Johannu.

"Ọmọ na si dagba, o si le li ọkàn, o si wà ni ijù titi o fi di ọjọ ifihàn rẹ̀ fun Israẹli" (Luku 1:80). Iwọnba nnkan ti a sọ fun ni ni yii nipa igba ewe Johannu. O n gbe inu iju o si n jẹ iba nnkan alai ni laari ti o le ri -- eeṣu ati oyin-igan. Ko bikita nipa nini ile ti o lẹwa ati aṣọ daradara. Iba aṣọ iwọlẹ ti a fi irun ibakasiẹ ṣe pẹlu amure awọ ni o n wọ̀.

### Iṣẹ-iranṣẹ Johannu

A kọ́ ni Ọjọ Isinmi ti o kọja nipa iye ọdun ti o gba Dafidi fun imurasilẹ lati pese rẹ silẹ lati jọba; lati igba ewe Samuẹli ni a ti kọ ọ lati di àyè iṣẹ woli. Nisisiyii a n ka a pe Johannu Baptisti jẹ ẹni ọgbọn ọdun ki o to waasu rẹ̀ ekinni, ni gbogbo akoko yii ni o si ti n mura silẹ fun iṣẹ ribiribi ti Ọlọrun ti ran an lati ṣe. Ọlọrun ti fun un ni aṣẹ nla kan, ko si gbọdọ kùna! Iṣẹ-iranṣẹ rẹ wa fun iwọnba oṣu mẹfa pere, ṣugbọn iru itan wo ni o ni lati sọ!

Fun ọpọlọpọ ọdun ni awọn Ju ti n duro de Messia ti Ọlọrun ṣeleri Rẹ̀ lati de. Wọn wà labẹ isinru awọn ara Romu, wọn n duro de ọjọ idasilẹ. Nigba miiran a dabi ẹni pe ọjọ naa ki yoo de. Lojiji Johannu jade wá pẹlu ihin idagiri pe Ijọba Ọrun kù si dẹ̀dẹ̀! Awọn eniyan naa ti yọ̀ tó! ọjọ idasilẹ wọn ti de wàyíi! Wọn rò pe Jesu yoo jẹ ọba aye ti yoo bi awọn alakoso Romu wó ti yoo si sọ wọn di ominira pada.

"Ẹ tún ọ̀na Oluwa ṣe, ẹ ṣe oju-ọ̀na rẹ̀ tọ́" ni ọrọ ti Johannu kede rẹ. Ko gba ogo kankan fun ara rẹ, ṣugbọn o wi fun awọn eniyan naa pe oun ni "ohùn ẹnikan ti n kigbe ni ijù," nipa ẹni ti Isaiah ti sọtẹlẹ (Isaiah 40:3). Awọn eniyan Ọlọrun ti ṣako kuro ninu ẹ̀kọ́ Rẹ̀ wọn kò si gbe igbesi-aye rere. Johannu wi fun wọn pe wọn ni lati ronupiwada ki wọn ba le wa ni imurasilẹ nigba ti Jesu ba de. Eyi ni o n sọ nigba ti o wi pe, "Ẹ tún ọ̀na … ṣe."

A mọ pe Jesu tun n pada bọ̀; awọn ọmọ Ọlọrun tootọ si n sọ fun awọn ẹlẹṣẹ lati ronupiwada ki wọn ba le ṣetan lati pade Rẹ̀ nigba ti O ba de. Awọn ti o fẹran Oluwa n mura wọn silẹ de ọjọ ti Jesu yoo de lati mu awọn eniyan Rẹ̀ lọ sile.

Ọpọ eniyan gbọran si iwaasu Johannu wọn si tọ̀ ọ wa ki a ba le ri wọn bọ omi, wọn si n jẹwọ ẹ̀ṣẹ wọn. Wọn n fẹ mura silẹ fun Ijọba Kristi wọn si n beere ohun ti wọǹ yoo ṣe lati mura wọn silẹ. Johannu wi fun wọn pe bi wọn ba ni ounjẹ tabi aṣọ ju iye ti wọn le nikan jẹ tabi lo tan ki wọn pin in pẹlu awọn ti ko ni tó. (Nigba gbogbo ni awọn ọmọ Ọlọrun mura tan lati ṣe iranwọ fun awọn alaini ti ko ṣe orire to bi ti wọn). Jesu wipe, "Niwọn bi ẹnyin ti ṣe e fun ọkan ninu awọn arakunrin mi wọnyi ti o kere ju lọ ẹnyin ti ṣe e fun mi" (Matteu 25:40). Awọn agbowode fẹ lati mọ ohun ti awọn yoo ṣe, Johannu si dahun pe ki wọn maṣe gba owo-ori ju iye ti o yẹ lati gba lọ lọwọ awọn eniyan. O wi fun awọn ọmọ-ogun pe ki wọn maṣe huwa ipá si ẹnikẹni, ki wọn si jẹ ki owo iṣẹ wọn to wọn. O ha ṣakiyesi pe gẹgẹ bi Jesu ti n fẹ ki awọn eniyan gbe ni Johannu kọ́ wọn? Olukuluku oloootọ oniwaasu ni yoo maa wi fun awọn ijọ rẹ pe wọn ni lati gbe lai lẹṣẹ, bi Jesu ti wi. Nigba ti O dari ẹṣẹ ji awọn eniyan O sọ fun wọn ki wọn maa lọ, ki wọn "ma dẹṣẹ mọ."

**Ironupiwada ati Igbala**

Awọn Farisi ati awọn Sadusi naa wá fun iribọmi Johannu ṣugbọn wọn ko ronupiwada. Wọn rò pe awọn dara tó nitori ti wọn n ṣe ifarahan pupọ bi ẹni pe wọn n pa Ofin mọ́. Ṣugbọn Johannu jẹ eniyan Ọlọrun tootọ o si ri i pe ẹlẹṣẹ lasan ni wọn. Ko si bẹru lati sọ fun wọn bẹẹ. O wi pe, "Ẹnyin ọmọ paramọlẹ, tali o kìlọ fun nyin lati sá kuro ninu ibinu ti mbọ̀?" Paramọlẹ jẹ ejo olóró, nitori naa iwọ le ri ohun ti Johannu fi awọn agabagbe pè. Johannu fi yé wọn pe wọn ko le wọ ijọba Kristi nipa iribọmi, lai si ironupiwada.

Awọn miiran wà lonii ti wọn rò pe koko ohun ti eniyan ni i ṣe lati mura tan fun Ọrun ni lati ṣe iribọmi, wọn lero pe iribọmi yoo wẹ ẹ̀ṣẹ̀ wọn nù. Ṣugbọn Jesu ati Johannu jọ kọ́ ni pe a ni i kọ́ ronupiwada ki a si gbà wa là kuro ninu ẹ̀ṣẹ wa. Nigba naa Jesu n fẹ ki a ṣe iribọmi "li orukọ Baba, ati ni ti Ọmọ, ati ni ti Ẹmi Mimọ́" (Matteu 28:19).

**"Ti O Pọ̀ju Mi Lọ"**

Johannu kò gberaga pe oun ni iṣẹ ribiribi ti o tó bayii lati ṣe, ati pe ọpọlọpọ eniyan ni o n jẹ ipe rẹ̀. O wi fun awọn eniyan naa pe ẹlomiran n bọ ti O pọ ju oun lọ. Ni tootọ Oluwa naa Ẹni ti o n sọ nipa rẹ pọ to bẹẹ gẹẹ ti Johannu fi rò pe oun ko yẹ lati gbé bata Rẹ̀ tabi lati ba A tu okùn wọn. Johannu wi pe oun ti fi omi Baptisi awọn eniyan naa, ṣugbọn Jesu yoo fi Ẹmi Mimọ́ baptisi wọn.

Gẹgẹ bi òye ti yé wa mọ, Johannu kò ri Jesu ri, ṣugbọn ọkan rẹ n fà si ọjọ naa ti Messia yoo de. Lọjọ kan bi Johannu ti n ṣe iribọmi ni Jọrdani, Ẹni ti a ti n reti pẹ́ naa fara han. Johannu ṣe ikede ti o larinrin ju lọ ninu iṣẹ-iranṣẹ rẹ: "Wò o, Ọdọ-agutan Ọlọrun, ẹniti o kó ẹ̀ṣẹ aiye lọ!" Gbogbo ireti irandiran ni a mu ṣẹ ninu ọrọ yii! Igba titun bẹ̀rẹ; saa oore-ọfẹ bẹrẹ.

**A Bẹ́ Johannu Lori**

Johannu ti gbadun aṣeyọri pupọ ninu oṣu mẹfa iṣẹ-iranṣẹ rẹ̀, ṣugbọn ki i ṣe gbogbo eniyan ni o fẹ iwaasu rẹ. Ọba ilu naa gbe obinrin kan niyawo, ẹni ti o ti ni ọkọ kan ri, ti ọkọ naa si n bẹ laaye sibẹ, ẹ̀rù ko si ba Johannu lati sọ fun un pe ẹ̀ṣẹ̀ ni. Eyi bi ọba ninu, o si fi Johannu sinu tubu. Ayaba binu pupọ si Johannu; nigba ti àyè si ṣi silẹ fun un, o mu ki a pa a. Johannu kú fun jijẹ oloootọ si Ọlọrun, ṣugbọn a mọ̀ pe o lọ si Ọrun lati gba èrè rẹ. Ọpọlọpọ awọn ajẹriku ni o ti mura tán lati kú dipo ki wọn fi igbagbọ́ wọn ninu Ọlọrun silẹ. Eyi ni itumọ jijẹ Onigbagbọ́ tootọ.

## AWỌN IBEERE

1. Iru ibatan wo ni Johannu Baptisti jẹ́ si Kristi?
2. Bawo ni Johannu ti dagba ju Jesu lọ to?
3. Ki ni ṣe ti a fi rán Johannu wá sinu ayé?
4. Ki ni ounjẹ Johannu ati aṣọ rẹ?
5. Njẹ a gba awọn eniyan là labẹ iwaasu Johannu?
6. Sọ diẹ ninu awọn nnkan ti Johannu kọ́ awọn eniyan.
7. Ki ni ṣe ti a fi bẹ́ Johannu lori?